# ABO IWADI IGBIMO IBILE IBADAN, ADELABU JEBI



AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hihu - ekin, Orere, Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS



ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6d
Obtainable at :-
A. B. AKINYẸMI
10A, Moloney Bridge St.,
LAGOS.



VOL. VIII No. 451. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, JANUARY 21, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)


## ABO IWADI IGBIMO IBILE IBADAN

ỌGBẸNI ADEGOKE ADELABU L'O DA'LẸ

irohin iwadi ọgbẹni E. W. J. Nicholson ẹniti a yan lati ṣe agbeyẹwo afisun rukuruku to ṣẹlẹ ninu ajumọṣe Ijọba Ibilẹ Ibadan yọju sita, a si fẹ fi ye awọn ọkawe wa ni ṣoki.

Oluwadi Ọgbẹni Nicholson gba pe Ogbeni Adegoke Adelabu Alaga Igbimọ na ati awọn merin miran oludamọran L. Ade Bello, Adewuyi, Bandele ati Adeleke Amọo jẹbi aiṣododo ati owo ijẹkujẹ.

Oluwadi gba pe Adelabu jẹbi owo ijẹkujẹ ninu afisun ti Ọgbẹni S. A. Akinyẹmi, Ogunṣola ti abule Ogunrin, ti Olugbọn Igbọn ati ti Ọgbẹni Adepoju Ọgbẹni Adelabu nikanṣoṣo lo da ọgbẹni Adepọju fi si aiye rẹ lẹhin igbati awọn igbimọ meji ti ni kia da duro, ko si ohun to le fa eyi ju nkan bi owo riba tabi ijẹkujẹ. Wuruwuru Adelabu a ma mu tayọ ọgbọn ori rẹ, a si ma ti hu'wa miran pẹlu girigiri ati Igbona ọkan nibiti o jẹ pe o to k'o huwa pẹlu ifarabalẹ ati lakaye.

Oluwadi yi ko gbagbọ wipe Ijọba Ibilẹ na le ni ori bi ọgbeni Adelabu ba wa lori aga rẹ. Ọna ti Adelabu yi nfi dasi iṣẹ igbimọ na t'aṣẹ bi ati ma nṣe nkan ni Nigeria, ko si si ibi ti iru rẹ gbe le ṣẹlẹ ni ilu Gẹsi.

Oluwadi gba pe Adewuyi Amoo ati Bandele jẹbi owo ijẹkujẹ ni ibudo ọkọ ni Ogunpa ati pe ọna ti Olu damọran L. Ade Bello gba fi ṣe Ade Contracts pẹlu Ijọba Ibadan ni kọlọfi ati aimọ ọwọ ninu.


(Wo iyoku l'oju ewe kejọ)



## THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited.

Ona tara ti enia legba lati di onişowo nilẹ Nigeria wa,
ni ile ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Ẹnikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ
aimoye awọn onişowo ilẹ Nigeria lara,
yala lati ma ta ọja fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa,
ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IṢẸ WA NI EKO :—

37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI : —

The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris,
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## T'OKO - T'AYA WUYE NILE IJEBU



CHIEF HON. T. T. ṢOLARU
THE BỌBAJIRO OF AGỌ - IWOYE, IJẸBU

Lati ọjọ kọkandinlogun oṣu kejila ọdun to kọja ni ero ti nwọ wọlu Owu ati Ago - Iwoye fun iwuye ti Ọlọla T.T. Ṣolaru, Bọbajiro Ago - Iwoye ati Iya-afin rẹ, Oloye A. Olu. Ṣolaru, Ọtunba Gbadesire, Owu Ijẹbu.

Larọ ọjọ Keresimesi to kọja ni eto ti bẹrẹ ni Owu fun Ọtunba Gbadesire, awọn ọmọ Owu, ti Ibadan si fi ilu ati ijo dabira nibẹ. Eto yi pari pẹlu isin ni Ile-isin St. Michael ni Owu l'agogo mẹwa arọ ọjọ kẹtadinlọgbọn, Alufa Agba I.O. Oluwọle lo wasu, akanṣe orin si waiye pupọ nibẹ.

Lẹhin eyi ni ariya gbẹrẹgẹjigẹ ni afin Ọba. Ninu awọn to ba wọn jọsin ni Ọba Olowu ati Olori rẹ, Ọba Ebumawe ati Olori rẹ, Ọba Akija ati Olori rẹ, Oloye Adekọgbẹ, Ọba Oloko ati awọn Ijoye rẹ Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati Oloye H. I. D. Awolọwọ, Ọgbẹni M.A. Ogun, F.A. Ṣoga, Bolujọ, J.O. Sanwo, Oloye T.A. Odutọla, Ọgbẹni-Oja Ijebu-Ode, Ọgbẹni S.O. Ṣonibare awọn ọmọ Owu fi Iwe Mimọ ati awọn abẹla gbadungbadun pataki ta Oloye lọrẹ nibi ariya na.

Gbogbo awọn ẹgbẹ lẹrẹṣirisi pẹlu awọn Ijoye lati Ago-Iwoye ṣe ayẹsi pupọ lọjọ na, awọn si nawo nara.

Ọlọla T. T. Ṣolaru ṣe iwuye tirẹ ni Ago Iwoye. Lọjọ kejidin logun oṣu Kejila ọdun 1955 lo le itẹ rẹ ati lẹhin gbogbo eto iṣẹdalẹ a ka itẹ na ni ọjọ kọkanlelọgbọn. Oloye Bọbajiro ati Ọtunba Gbadesore si papọ ṣe idupẹ ni ọjọ kinni ọdun yi ni Ile Isin Eleto Agọ Iwoye. Alufa agba E. A. Adubifa lo ṣe iwasu, ifẹ kun, ita kunpe gbogbo ẹṣẹ ẹgbẹ Agọ-Iwo lo


(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# ITAN IDILE QBA OYINBO GESI

## IFI QBA KAN JE LORI GBOGBO ENIA JE QNA OGBOLOGBO TI WQN TI GBE KALE NI ILE GESI

Gẹgẹbi a ṣẹ ngbọ kikankikan ni ojojumọ nipa irin ajo ibẹwo ti Ọba obinrin Ilẹ Gẹsi yio ṣe wa si Nigeria ni oṣu kinni ọdun titun, a fi akoko irohin ti ọsẹ yi silẹ lati sọ nipa awọn idile ọba yi ati ọkọ rẹ.

Fun bi ẹgbẹrun ọdun ni wọn fi njọba ti kinni-kan ko yingẹ. Ni arin akoko yi ewẹ, nigbati rogbodiyan ati ija igboro bẹ silẹ, ọgbẹni Oliver Cromwell gba ijọba lọwọ ọba ti a npe ni Charles ikinni. Akoko ti a mẹnu ba fẹrẹ yi nlọ bi ọdunrun ọdun o le mẹfa s'ẹhin

Biotilẹjẹpe ikuna diẹdiẹ ti wa nipa ifi ọba jẹ, sibẹ-sibẹ wọn ko tii fi ilana atọwọdọwọ wọn silẹ nipa idile ọba. Ẹni ọ'anla Elizabeth II. ti o jẹ ọba nisisiyi jẹ ti idile ọba Egbert, ti o sọ gbogbo England di ọkan bi ẹgbẹrun ọdun le mọkanlegbọn lẹhin iku Oluwa s'ẹhin.

Ọkan ninu idi fifi ọba jẹ ṣe ni iduroṣinṣin bayi, ni wipe ofin ijọba Ilẹ Gẹsi wa labẹ idari awọn enia. yatọ si ofin ati aiye de aiye ti awọn ẹlomiran ki ifẹ yi pada. Ohun ti eyi si fi ṣe pataki ni wipe, bi igba ba nyi pada ni awọn enia na tun le ma gba ero titun jade ninu ofin lailai iyipada ninu eto atọwọdọwọ, bibẹkọ, ẹniti o ba mu iru idigbolu yi wa yio ba ara rẹ niwaju adajọ.

Ninu imulẹ ofin ti wọn fi lelẹ nipa fifi ọba jẹ ni igba ọdun-le-ni ọgọta s'ẹhin, wọn fi lelẹ wipe ọba obinrin Ilẹ Gẹsi yio ma jẹ ẹya ara ẹni ọmọ Julọ, ọmọ-ọba Sophia ti iṣe ọmọ-ọmọ ọba James kinni, ati wipe gbogbo awọn ẹya wọnyi yio ma sin ẹsin Igbagbọ. Nisisiyi bi iyipada ba ni lati wa ninu ipinu ti wọn ti gbe kalẹ yi, o nilati ti ọwọ gbogbo enia ati gbogbo orilẹ aiye ti o ba njọba le lori wa. Nipa ilara yi ẹwẹ, agbagba ni awọn ọba fi ngori oye.

Nigbakugba ti ọmọ obinrin ọba ilẹ Gẹsi ba gun ori oye, nṣe ni wọn ma ifi gbogbo agbara ijọba lee lọwọ gẹgẹ bi ọba. eyi si ni idi ti wọn ki fi ka ọkọ wọn bi ọba, i bi o ṣe fi ara han nisisiy. ninu ijọba Elizabeth keji Ofin ijọba ko fun iru awọn ọkọ bayi ni ipo pataki kan ninu eto ijọba. Sugbọn bi ọba obinrin ba gbe iyawo, iyatọ a ma wa nitoripe iyawo yio wa bi ọba obinrin titi orun ijọba ọkọ rẹ yio



Queen Elizabeth II.

fi wọ.

Bi ọba kan bawaja ki si iyapa ninu eto igori oye, ẹsẹkẹsẹ ni igbimọ ti o nfi ọba jẹ yio pesẹ pẹlu awọn enia nlanla ni ilu London, ati awọn aṣoju ti o wa ni abẹ asia Gẹsi ati awọn orile ede miran ti o wa ninu ẹgbẹ kanna pẹlu rẹ; ninu ipade yi ni wọn yio si ti yan ọba miran. Bakanna ni wọn ti nṣe iwuye bi ẹgbẹrun ọdun s'ẹhin. Ninu eto ti wọn fi ṣe iwuye ọba Edgar ti Bath bi ẹgbẹrun ọdun-din-mẹta-di-lọgbọn lẹhin iku Oluwa wa s'ẹhin ni wọn ti yọ ilana iwuye ọba ti o wa lori igunwa nisisiyi.

## Idahun Si Ibere

Olotu,

Gba mi laye lati dahun ibere Ọgbẹni David oyewọle ara Abidjan ti o jade ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ.

Awọn mẹtẹta ni o gbiyanju daradara, ṣugbọn eyi to ko ma si ọwọ mejeji ti ti o mu okun lọ si isalẹ ki o to jade ti omi ko si kan lara ni o ṣe ju, ninu ero ti emi

Emi ni
G. A. Olanrewaju

No. 12

# AKIYESI PATAKI

A ṣe ikede yi lati ile-iṣẹ Akọwe Agba Ijọba wipe, pipin awọn Iwe Ijoko (Tickets) fun oriṣiriṣi ariya ti ao ṣe ni gbogbo asiko ti Alaiyeluwa Ọba Obinrin yio lo nilẹ yi, lọdọ awọn Ẹgbẹ pataki-pataki ni a ti nṣe, a ko si ni da ẹnikẹni ti o ba kọwe fun Iwe ijoko si ile-iṣẹ Akọwe Agba Ijọba (Chief Secretary's Office) lohun.

A si tun fi eyi sọ wipe Iwe ijoko kan wa fun ẹnikanṣoṣo ni, ako ni gba ju ẹnikan lọ fun iwe ijoko kan. (Ati wipe ẹniti o ba ni Iwe ijoko kan ko gbọdọ mu ọmọde dani pẹlu ararẹ)

No. 11

# DOMESTIC SCIENCE CENTRE, 13, IDOLUWO STREET, LAGOS EVENING CLASS: 1st TERM, 1956

Evening Classes open to adult women will commence on the 23rd January, 1956 at the above Centre.

| | | | |
|---|---|---|---|
| Dress-making | : Mondays and Fridays | 5 - 8 p.m. | - Mrs. A. Akerele |
| Millinery | : Thursdays | 6 - 8 „ | - „ T. Akinyemi |
| Cookery | : Wednesdays | 6 - 8 „ | - „ Yesufu & or „ Akigbehin |
| Embroidery and Knitting: | Tuesdays & Thursdays | 6 - 7 „ 6 - 7 | - Mrs. H. Osibo. |

Applications for admission by letter or interview the Woman Education Officer in-charge Domestic Science Centre, 13, Idoluwo Street, Lagos.

Fees of 15/- for each course are payable in advance.




## Mo B'olomo Yo

A ṣe ikomọ jade ọmọ obinrin ti Ọlọrun fi ta Ọgbẹni Amusa Raji alapata ẹran ni Ọja Araromi pẹlu iyawo rẹ lọrẹ ni ile wọn ni 32, Agbo-malu (Cow Lane) Eko.

Awọn ẹbi Baba ọmọ ati iya ọmọ na pejú-pesẹ nibi ikomọ na. Orukọ ti wọn sọ ọmọ na Sẹrifatu Abẹkẹ.

Lẹhin is'ọmọ l'orukọ ni faaji bẹrẹ, iya ọmọ na, Falilatu Abẹkẹ ati Baba ọmọ fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo enia l'ọrun. Aka pẹlu awọn ọrẹ rẹ fi orin asiko dara, ti ijo nṣe rọnyin titi ilẹ fi ṣu.

Awọn gbajumọ to wa sibi ikomọ na ni awọn enibi Ọgbẹni Raimi Onifade, A. Afọlabi, Salami Adedeji, Sule Ẹlẹmọrọ, Lamina Majagun ati A. Batula.

Ki Ọlọrun da ọmọ na si o.

## Idahun Si Oro Ogbeni G.A. Maku

(O bẹrẹ ninu iwe wa ọsẹ tokọja)

Nipa ti orukọ ti ẹwi, nitotọ o ni lati ri bẹ fun yin, mo rope o dara ki ẹ ma ba awọn gbajumọ to gbajugbaja rin ni Oke Ọdẹ tabi Eko. Sugbọn mo gba wipe otitọ ni ọrọ awọn Baba wa pe, Ọmọde kan koni ni aṣọ to agbalagba, ko tun ni akisa to tabi julọ. Oluwa ma ṣe gbogbo wa ni alakisa ninu ọdun yi titi lọ o. Sa agbara dada, Iwọ yio gbọ kulẹ kulẹ ẹniti o njẹ S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ. Onile ni emi ni Oke-Ọdẹ, ti mo ni Iya ati Baba nibẹ, nki iṣe alejo rara. Baba nla Iya emi S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ ni o kọkọ jẹ Ọba ni Oke-Ọdẹ, orukọ rẹ a majẹ "Balẹ Agbera" Balẹ Agbera na ni o bi Adeọba Adeọba ni o bi Salu, Salu ni o bi Iya emi S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ.

Salu jẹ Ọba ni Oke-Ọdẹ Ori oke, o si sọkalẹ lati Oke-Ọdẹ ori oke na wa si Oke-Ọdẹ Agodongbo, dide Oke-Ọdẹ yi, awọn ọmọ rẹ ba sọkalẹ wa si Oke-Ọdẹ agodongbo ti a wa loni yi. Nigbati o si ti de si Oke-Ọdẹ agodongbo, lẹhin ọdun meje ni awọn to wa ni Oke-Ọdẹ, ori oke ṣẹṣẹ wa si Oke-Ọdẹ agodongbo ti a wa yi,. Lẹhin ọdun karun ti gbogbo wọn ti kuro l'ori Oke-Ọdẹ ti oke tan, ni Salu ku. Lẹhin iku Salu Baba Iya mi, wọn fi Baba Saata jẹ oye Balẹ, Baba Saata lo ọdun mẹsan lori oye o si ku. Lẹhin iku Baba Saata wọn wa fi Muhamadu jẹ Ọba Muhamadu si jẹ ọmọ Salu. Nigbati Muhamadu ku tan ọmọ rẹ ni a fẹ ki o j'ọba na. Mo si le sọ pe ninu awọn agbalagba wa ti wọn nfi ọba jẹ tabi Ijoye, ẹhin ọmọ Muhamed ti a wi yi ni wọn wa.

Baba yin agba to njẹ Maku na, lobi Onijato, Onijato lo si bi Owolabi, Owolabi lo si bi Bello Lapinni. Lati Ibẹre orukọ yin yi, to berẹ lati Baba yin agba ko si Ijoye ninu wọn de'po Ọba. Ha a rara ati rara, ko si ninu wọn.

Ohun ti ẹ si le fa bi ẹ ba fẹ sọrọ rara, ni iṣẹ ọna ṣiṣẹ ni oke-Ọdẹ, nitoripe, iṣẹ Baba yin agba ni Oke-Ọdẹ ni iṣe ọna to ba dabi irọ. kiẹ tun bere lọwọ awọn agba yin.

Imọran ni eleyi fun Ọgbẹni G. A. Maku kiẹ ma ṣe jẹki a ma fi otitọ pamọ nitori ọtẹ.

Gẹgẹbi ẹ ti sọpe G. A. Maku ni ẹnyin njẹ, emi ko ni ero wipe ninu nwọn, a le ri ọkan ni Eko, kini tiyin ṣe jẹ?

Adura fun gbogbo enia lọmọde, lagba, ni'joye, ati ni Ọba ti wọn sọpọ mọ Oke-Ọdẹ nile ni, loko ni, gbogbo bi wọn ti ṣe le dagba to, Oluwa majẹ ki wọn mọ sare Ọmọ wọn, Oluwa ko ẹ a gbogbo wọn si di igbamiran, bi esi ba wa mo nreti o.

Emi ni
S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ.

## Awamoto To pa'nia Salo

IBADAN– Ni gbati nwọn nṣe iwadi iku ti o pa arabinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Ẹgbẹyẹle Amọkẹ ni ọja Mọkọla nilu Ibadan, ni ọlọpa sọ wipe awọn nwa Awamọto ti o pa obinrin na.

Ọkọ obinrin na, Samuel Akande, alagba bi ẹni ọdun marunlelọgọta pẹlu omije loju ni o fi nsọ niwaju ọgbẹni H. B. Ọbafẹmi ti nṣe oluwadi iku obinrin na wipe on ko mọ pe arimọ ni on ri iyawo on nigbati o jade lọ si ọja l'ọjọ na. Oluwadi pari ọrọ rẹ wipe obinrin na ku iku ifarapa jamba mọto.

Awọn ọlọpa ṣi nwa ẹniti o wa mọto pa obinrin na nisisiyi o.

## Esi Si Ibere

Olotu,

Gba mi laiye lati fesi si ibere ti o jade ninu Iwe Irohin rẹ oloyinmọmọ

Awọn mẹta ti o rekọja lori omi. Awọn agbalagba ma npa lowe wipe ẹni meji ki irin l'oju ọna ki ẹnikan ma ju ara wọn lọ.

Ẹniti o bẹ omi si meji ni o lagbara ju, gẹgẹbi ero ti emi.

Emi ni ti yin,
Young Ọla Kasumu


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)

O wa lọdọ :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

## FUN FIFO EHIN FUNFUN DARA-DARA ATI IGBADUN ENU




Ma Lo Egbogi **COLGATE** Chlorophyll Ti A Fi Nfo Ehin.

Ma fi egbogi Colgate Chlorophyll ti a fi nfọ ehin fọ ehin rẹ nigba gbogbo. Iṣẹ iyanu rẹ ko mọ lori ki ehin rẹ ma bajẹ, ki o mọ, ki o si fun-fun nikan, o tun npa kokoro ehin, ko si ni jẹki akokoro yọ'nu.

Ri daju pe o nlo egbogi Colgate Chlorophyll ti a fi nfọ ehin nigba gbogbo. Egbogi alawọ ofefe ti nbo bi ọṣẹ.




Bere egbogi ti Colgate alawo ofefe ti a fi nfo ehin

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos — "ELETI - ỌFẸ LAGOS"
P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL. VIII. NO. 451. LAGOS, SATURDAY JAN. 21, 1956.


## Arikogbon Ni Abo Iwadi Igbimo Ibile Ibadan

Ko yẹ ki a ma f'ẹnu kan abọ iwadi ti Ọgbẹni B. W. J. Nicholson ti iṣe oluwadi Igbimọ Ibilẹ ilu Ibadan ṣe l'ori ẹsun ati rudurudu to ṣẹlẹ ti ko jẹki iṣẹ Igbimọ na ṣe dede.

Gẹgẹbi gbolohun ti a fi ṣe akọlẹ s'oke wosika wa yi wipe arikọgbọn ni eyi nilati jẹ fun awọn Igbimọ miran, ani, awọn ti a yan gẹgẹbi Olugbimọ tabi awọn ti a fi ṣe olori tabi alakoso Igbimọ, ki olukuluku so agbejẹ mọ'di, ki nwọn maṣe jẹki ipo ọla na gun wọn lati rekọja aye wọn.

Nisisiyi ti abọ iwadi Igbimọ na jade yi, o fi han gedegbe irufẹ awọn enia ti nwọn jẹ pataki ninu Igbimọ na, gẹgẹbi irohin abọ iwabi Igbimọ na ti a ṣe sinu iwe wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa, ohun abuku pataki ni eyi jẹ fun wa, papa awọn enia ti iṣe olugbimọ Ibilẹ Ibadan.

Ireti tiwa nipe awọn Olugbimọ ilu Ibadan na ko ni jafara lati ṣe eto ilana ti Oluwadi la silẹ fun wọn ati imọran ti Ijọba Iwọ - Orun gba wọn wipe "Iyẹ ti ko ba dara lara ẹiyẹ, ẹiyẹ ntu danu ni" atunṣe di ọwọ yin o.

Arikọgbọn ni abọ iwadi ti Oluwadi Igbimọ Ibilẹ Ibadan ṣe jẹ fun ẹniti o moye. Iyẹn bẹ.

BI AIYE BA KỌNI, ỌRUN AGO O, NI A TUN WI.

Awọn baba wa mọnimọni nilẹ Yoruba, ani, awọn akọni enia, ni nwọn ma npa l'owe wipe, "bi aiye ba kọni, orun ago ni a tun wi" njẹ nisisiyi ti idajọ Kotu meji tako iwa ati iṣe Ọgbẹni Adegoke Adelabu yi, ko ha tọ ko ha yẹ ki Ọgbẹni Adelabu fi iṣẹ iṣelu silẹ, ki o fara ṣ'oko fun igba diẹ, nitoripe awọn Oniwaka Imale ni nwọn ma nkọ orin waka wọn na bayi wipe:-

"Eyi to'ronu f'ẹni to moye"
Itiju pa wọn, arẹ epe ni o.

No. 6

## PUBLIC NOTICE

It is notified for general information that the Lagos office of the Government Valuation Unit will be closed down as from 14th January, 1956.

After that date all matters relating to rating assessments will be dealt with by the Assessment Section of the Town Engineer's Department, Lagos Town Council.

## Polowo Ọja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ọfe

No. 9

## "PUBLIC NOTICE"

### MEDICAL DEPARTMENT

Vacancies for Government Student Nurses In Lagos Preliminary Nurses Training School Lagos

Applications are invited from girls of Mordern II Standard and upwards for entrance to the Goverment Nurses Preliminary Training School, Lagos commencing in April, 1956.

2. All applications with details of educational testimonials should be made in writing not latter than 15th February, 1956 and marked "CONFIDENTIAL" and addressed to the :-

SENIOR MEDICAL OFFICER,
27, KAKAWA STREET,
LAGOS.

3. The applications should be accompained with the following documents :-

(a) Copy of School Leaving Certificate Mordern II or Government Secondary IV, V or VI.

(b) Copy of Birth Certificate.

(c) Copies of three recent testimonals (one from Headmaster or most recent employer).

4. Unsuitable applicants will not be notified; suitable candidates asked to report for interview bringing Original Certificates and Testmonials for perusal.

5. The course lasts six months with subsistence allowance of £7 per month and successful students thereafter procced to the General Hospital, Lagos or Massey Street Dispensary as Nurses and/or Midwives-in-training for a further period of three years.

SENIOR MEDICAL OFFICER, LAGOS.

No. 73/S. 2./Vol. V/963.

## Royal Routes In Ibadan

The following routes will be used by the Royal Party during the Visit of Her Majesty the Queen to Ibadan:

SATURDAY, 11th FEBRUARY.

(a) ARRIVAL AT IBADAN BY TRAIN: Ibadan Railway Station to Government House Via Dugbe, Ekotedo, Mokola and Hammock Road.

(b) OFFICIAL RECEPTION AND INVESTITURE: direct route to the Western Hall from Government House. Return by the same route.

SUNDAY, 12th FEBRUARY.

Free Day.

MONDAY, 13th FEBRUARY.

(a) RALLY AT THE RACECORUSE: Government House to Racecourse via Hammock Road, Mokola and Saben Gari.

(b) MOOR PLANTATION: from the Racecourse via Stones Road, Dugbe and Lagos Road to Moor Plantation. Return via Railway Station, Dugbe, Ekotedo, Mokola and Hammock Road.

TUESDAY, 14th FEBRUARY.

VISIT TO FEDERAL INSTITUTIONS OF HIGHER LEARNING: Government House Via Hammock Road to University College Teaching Hospital; thence via Mokola and Oyo Road to the Nigerian College of Arts, Science and Technology, thence to the University College via Oyo Road. Return to Government House via "Aerodrome Road" (Bodija Crossing)

WEDNESDAY, 15TH FEBRUARY.

(a) OPENING OF NEW PARLIAMENT BUILDING: Government House via Hammock Road to Bunny's Leap, thence via the new dual carriageway direct to Parliament Building. Return to Government House through Agodi - shortest route.

(b) DEPARTURE FOR IJEBU-ODE: from Government House to Taffy Highway then via Bere Square and Mapo Hall, down Isale Ijebu and thence to the Ibadan - Ijebu-Ode Road.

Maps shewing the Royal routes for each day will be included in the Official programme which will be published in due course.

## Oku Ọlọmọ, Gege L'ao gbe

Ọkan ninu alagba ijọ Eleto ni Agbeni, Ibadan ni Victoria Odutọla jẹ ko to jẹpe ikẹhin ni ile rẹ ni Isalẹ Osi lọjọ kini ọdun yi. Olufọkansi gidigidi ni Ologbe na jẹ ko to di pe arẹ ara ko jẹki o wa si ile isin tobẹ mọ o si ku ni ẹni adọrun ọdun.

Ninu awọn ọmọ ati ọmọ-ọmọ to ṣẹhin de ni awọn Iyaafin Dorcas Ibipọ, Muniratu Ibironkẹ Davies, Falilatu Adukẹ Ajigbaiye, awọn Ọgbẹni Tunji Afun Ajibowu Coker, Lasisi Akorede Abinuwaiye ati Omidan Modupẹ Agbẹkẹ Afun.

Awọn ọmọ Oloku wọnyi fi ti ijo tẹyẹ sin iya wọn de itẹ, jijẹ ati mimu si buaiya pupọ. Wọn ku inawo Oluwa ko jẹki ẹhin iya k'o dara, ki Ọlọrun gbe si afẹfẹ rere.

Ninu awọn to wa sibi oku na ni Oloye J.O. Ade Craig, Ọgbẹni S.A. Ọlọkọ, M.B.E., J.O. Laniyọnu ati Iyaafin rẹ Akinlọtan, James I. Afun S.G. Iṣọla, S.A. Ọjẹtunde, A. Ọlawọye, Ladele Ọlọkọ Popo Ẹkun, Akanni Olorode, Dọja, Ajibọla, Lamidi Apanpa, Amofin Durosaro, Ajadi Oniga, Rasik Davies, A.B. Mustafa, Alhaji Amusa, A.R. Asuni, Raimi Layanju, Alhaji Inakojo Modupẹ Akanbi, Salami, Ayinde ati awọn Iyaafin Ayinkẹ Ayinkẹ Marquis, Joko, Ogunade, Awero Iyanatu, Adukẹ Ojobarọ, Ayọka Oyemade Adeoti Ẹkun, Adepele Inakoju, Konibire Gbọlade, Raliatu Abikẹ Ẹkun, Moyọsọrẹ Adukẹ Mustafa, Atinukẹ Akinloye, Durosaro Monilọla Akinloye Madandọla Ọlọkọ ati Atọkẹ Ọlọkọ.

## Adura Ose yi

Oluwa ṣanu fun wa, maṣe fi onjẹ ọjọ wa du wa, fi alafia ara ta wa l'ọrẹ, ki o si fun wa ni ẹmi imore si Ogo rẹ.
Amin

## Oloye Falana
### Babasale Onigbagbo Ku

Ni ọjọbọ ti ọjọ karun oṣu yi ni a gbọ iku Oloye D. A. Falana Babasalẹ gbogbo Onigbagbọ ni ilu Ibadan ati ọkan ninu adajọ ibilẹ. Ẹni ọdun mejileladọrin ni ologbe na, gbo gbo awọn ijọ Eleto ti ilu Ibadan ni wọn parapọ bi awọn ọmọ ti ko tun ẹhin oloye na ṣe. Ẹyẹ ọjọ na pọ ti awọn ologbon ti Oyinbo ṣe iyesi igbẹhin fun u lati ile rẹ titi de ile isin de itẹ pẹlu. Ero pọ lapọju, ẹse ọarọki ilu pe sibẹ.

A SO ENIA KUKURU DI GIGUN
[illegible]
ACTIVITIES (D 112)
Kingsway, Delhi-9 India



Make your house
"FIT FOR A QUEEN"
...decorate now with
PAMMASTIC
PLASTIC EMULSION PAINT
"The Plastic Paint of the Atomic Age"
S·C·O·A Branches throughout Nigeria

## Eniti Ko Fi Tolorun Se. Ako Aja Lo Ngbo

Lati Ọwọ ẸṢỌ IKOYI

Bi enia ba nsọrọ, o yẹ ki o ma fi ti ogo Ọlọrun pẹlu. Nitoripe ohun ti Ọba Ọlọrun ko ba fẹ, ohun na ko ni ṣe titi lai nitori:-

1. Bi igi ti tobi to, bẹ kọ ni ọrọ inu rẹ nto, On la da fun Gbẹna-gbere ti nṣe ọmọ Ọlọfin; Lọjọ ti o nlọ bẹ gbogbo igi oko,
 A ni ki o tilẹ duro rubọ. O kọ wipe on ko ni ru. Bi on ba ti rubọ akọ igi, iyoku buṣe.
2. Ojumọ mọ, Gbẹna-gbere di iba mọ iroko, o bẹ ẹ, O di iba mọ Ẹgungun, o bẹ ẹ, o wa lọ diba mọ Oiro ṣikẹta. Ilẹ ṣu, o ni bi ojumọ ti nmọ lọla ni on yio bẹ igi Oiro. Ilẹ mọ, Oiro di akanti. Ọwọnrin-meji.

Nigbati ilẹ ṣu, Ọrọ inu igi Oiro jade, o nke ibosi Gbẹna-gbere kakiri inu igbo. Bi ọrọ na ti nke ibosi kiri, Iku gbọ ohun rẹ, o jade wa bere wipe, kiloṣe ọ ti o fi nke bayi ? Ọrọ inu igi Oiro r'ojọ wipe, igi ti on gbe inu rẹ ni Gbẹna-gbere ọmọ Ọlọfin diba mọ ti o si mbọ wa ge lulẹ ni ọla yi. Iku tun bere wipe, njẹ Gbẹna-gbere na, ko ha yọ ti on iku kuro bi ? Ọrọ na si dahun wipe, bẹni, o yọ tirẹ kuro. Arun tun jade, o bere bakanna. Ọrọ igi Oiro tun wi fun pe, o yọ tirẹ kuro pẹlu. Iku ati Arun si wipe, niwọn igbati o ti yọ tiwa kuro, ti wa ko si nibẹ mọ niyẹn.

Bi Ọrọ yi ti tun rin siwaju diẹ, bẹni o pade Ọran Ẹburubu, o bere wipe kini ohun ti o de si ọ ti o fi nke kiri bayi ? Ọrọ igi Oiro tun ko ẹjọ, o ro wipe, Gbẹna-gbere ọmọ Ọlọfin lo diba mọ iroko, Araba ti o si ge gbogbo wọn lulẹ, ṣugbọn nigbati o di iba mọ igi ti on ngbe inu rẹ lati ge ilẹ ti ṣu, o si ṣeleri lati wa ge igi on lulẹ lọla. Ẹ dakun ẹ gba mi.

Ọran Ẹburu tun bere lọwọ ọrọ igi Oiro wipe, njẹ o ha yọ ti on kuro ndan? Ọrọ na dahun wipe rara! nko gbọ ki o yọ tirẹ kuro. Inu bi Ọran Eburubu, o si ṣeleri wipe, bi o ba jẹ wipe bẹ lọrọ ri, njẹ ko ni r'oju bẹ igi na lọla; lotọ, lotọ, fun iwọn oṣu mẹta gbẹna - gbere ko ro'ju lati ke igi Oiro ti o di ba mọ. Bi Ọran ẹburubu ti nyọ si lọtun bẹni o nyọ si losi.

Nigbati ọrọ ẹburu yi kaseta fun Gbena - gbere tan, idamu ile ati tode ko jẹki o ranti igi Oiro ti o diba mọ. ọkan rẹ poruru o wa tọ awọn Babalawo lọ lati yẹ ifa wo. Babalawo na bere wipe, njẹ iwọ ko ha di iba mọ igi kan lati ge e bẹ? Nigbayi ni o ranti igi Oiro ti o diba mọ, a ni ki o ya lọ mu igiripa obukọ kan ati ẹgbaxan wa, ki o si yara lọ tu iba na, ki ọrọ ẹburubu le tan lọrun rẹ. o gbọ o ru.

Eyi ni awọn Onigbagbọ fi kọ wa wipe, ko dara ki enia ma sọrọ tabi ki o ma ṣeleri laifi ti Ọlọrun pelu. Awọn Imale nigbati nwọn ba nsọrọ, nwọn o ma wipe pẹlu Ogo ti Ọlọrun tabi lagbara ti Ọlọrun, ogo ṣe ohun bayi - bayi, Nitoripe Ọba Oluwa ni Alewileṣẹ, on nikanṣoṣo lo le wi bẹ on nikanṣoṣo lo le pe ara rẹ ni Emi.

Eyiyi ni awọn baba wa ri ti nwọn si fi n pa owe bayi wipe l'ogo Oluwa, igbẹhin a dun. Ohun kohun ti enia ba fi ti Ọlọrun ṣiwaju, daju - daju igbẹhin rẹ ni lati dun.

## Oga Ile Iwe Fi Adota Ponun Se Owo Ibole

IBADAN— Nigbati ọga ile-iwe kan lọ ri Olotu Ẹkọ Iwọ-Orun, (Minister of Education) ki nwọn le tun Ile-Iwe rẹ ti wọn ti lori aiko dọgba pẹlu ofin Ẹkọ ṣi pada, ni o ba fi ọgbọn yọrọ apo-iwe meji (Two envelopes) silẹ, ọkan kun fun iwe ti o kọ nipa ile-iwe rẹ na, ekeji si kun fun Iwe-Owo ( Currencey Notes ) adọta Pọnun.

Laiko d'ena p'ẹnu Ọgbẹni S.O. Awokọya ti iṣe Olotu Ẹkọ ni Iwọ-Orun, ranṣẹ pe Ọlọpa ki o wa ba on fi oju ofin wo ọrọ na, gẹgẹbi Ọga ti o njẹ Ayọọla Fakankun ti iṣe Ọga ile-iwe giga ti ilu Ọyan yi mu on binu nigbati o nfẹ fi owo ibọlẹdi on l'ẹnu.

Olotu Ẹkọ Iwọ-Orun si tun sọ fun Adajọ wipe Oga ile-iwe na mu ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Adamọlẹkun wa si ile on ni ọjọ na.

Adajọ fi ẹjọ na si igba miran.

## Awon Ikilo Die Nipa Qba Obirin To Mbo

Aṣa mofẹ - mofẹ, aṣa mokọ - mokọ, aṣa ki a gba ni leti lẹmẹfa, ka fi ẹ ẹfa le ni lọwọ. Awọn gẹsi ko fẹ ki ohun abuku kan ta le ọba wọn. Iṣe ti a nṣe, ati iru iwa ti a nhu si awọn ọba ilẹ Nigeria, a ko gbọdọ hu'wa bẹ si ọba gẹsi. Diẹ ninu awọn nkan ti o jẹ abuku fun ọba Gẹsi niwọnyi:-

1. Bi ọba Gẹsi ba mbọ l'oju ọna, a ko gbọdọ wa mọto tabi ki ẹlomiran rin ni oju opopo kanna pade rẹ rekọja, abuku lojẹ.
2. Bi o ba mbọ wa, ẹnikẹni ko gbọdọ sare kọja loju ọna ti ọba yio rin lati ibikan bọ si ibikeji.
3. Ẹnikẹni ko gbọdọ fi ọwọ ofifo gbọwọ lọwọ ọbo ayafi ki o fi ibọwọ si ọwọ.
4. Ẹnikẹni ko gbọdọ mi ọba lọwọ tabi ki o di mu pẹnpẹn.

(Wo y'oku l'oju ewe keje)

Mo Gbadun Siga Pirate



## Irora Lakuregbe

Iwosan rẹ lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwosan ti o daju kuro ninu irora Lakuregbe, o yẹ ka tete fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindinrin oluwa rẹ ko ṣiṣẹ to, o nfẹ iranlọwọ. Nitori iru amodi bayi lati ṣe ṣegbogi DE WITTS, yio si fun enia ni igbadun ara.

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nṣe iwosan Lakuregbe, danwo, ki o lọ ra ọkan ni ṣọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba ṣiṣẹ tara, ṣugbọn bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio de si oluwa rẹ, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti ṣiṣẹ. Danwo lọ ra ni ṣobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles



## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.

Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

30/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN



## Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun Germany to ṣeṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.


## Akiyesi Fun Awa Moto




Ẹnyin awa Mọto, ẹ ṣe akiyesi aworan oke yi ki ẹ ranti wipe iṣọra pupọ ni ẹ nilati ṣe ni asiko ti Ọba Alaiyeluwa, ti ilu Oyinbo mbọ wa bẹ ilu wa wo yi.

Ogo ati iyin ni yio jẹ fun wa gẹgẹbi Orilẹ-ede Nigeria ti ko ba si jamba Mọto kọ lu'gi-kọ l'ọpẹ nigbogbo asiko ti awọn ẹni-ọla nla Alaiyeluwa Ọba obinrin ati ọkọ rẹ yio lo ni ilu wa.

Ẹnyin Awamọto, o di ọwọ yin o!

## Ko Si Ọba Ni Ilu Ejinrin

Emi ri iwe irohin kan, ti o jade ni ọjọ kesan oṣu Jan, 1956.

Ọrọ na nipe, ọkunrin kan ti a npe ni Saka Ọdunitan, ẹniti o nfi ara rẹ jẹ Oye Ọba Elekuru, wipe, on ni Otun ba-lofi ko si ohun kan ti o jọ bẹ ni ilu Ejinrin ri rara. Balẹ ni oye ti a njẹ ni ilu Ejinrin. Ọkunrin ti a npe ni Saka Ọdunitan yi gan, Balẹ ni Baba rẹ ẹniti orukọ rẹ njẹ Ọdunitan jẹni Ejinrin, ki o to ṣalaisi.

Ẹniti o sọ pe, o fi on jẹ oye yi gan Ọta ni on pẹlu Baba rẹ Ọdunitan jẹ wọn ti fi ara wọn si Court ri ni Eko, ati pe orukọ oye ti a nwi yi "Ọtunba-lofi" Saka Ọdunitan ti fi orukọ na pe ẹjọ ni Supreme Court Lagos, Suit No. 154/1948 ti o si jẹbi nitoripe ko ba ẹniti a npe ni Lofi tan rara.

S. Ade Ologudu

## AWỌN IKILỌ DIẸ NIPA ỌBA OBINRIN TO MBỌ

(obẹrẹ loju ewe kẹta)

5. Obinrin ti o ba fẹ lọ gbọwọ lọwọ ọba, yio ma lọ tara sọdọ ọba, nigbati o ba ku bi iwọn ẹsẹ mẹfa ki o de ọdọ ọba, yio duro, yio si tẹ ki ọba bi eyiti o fẹ kunlẹ, yio dide yio tun rin sumọ ọdọ ọba yio tẹ bakanna. Bi o ba ki i, ko gbọdọ yi pada tabi ki o kọ ẹhin si ọba. Ṣugbọn yio fi ẹhin rin to bi iwọn ẹsẹ mẹfa, yio tun tẹ ki ọba, nibin ni yio ti yi pada kẹhin si ọba yio si ma ba tirẹ lọ.

6. Bi oba ba jẹ wipe Ọlọpa, tabi Sọja tabi Ex-Service ni oluwa rẹ ti o ni lati lọ ki ọba, yio ma lọ tara sọdọ ọba, nigbati o ba ku bi iwọn ẹsẹ mẹfa ki o de ọdọ ọba yio bẹri, yio tun rin diẹ siwaju yio tun bẹri, nigbana yio ki ọba. Bi o ba ki tan yio tun rin ẹsẹ mẹta sẹhin yio tun bẹri, lẹhin eyi yio yi pada ma lọ.

## Ẹnyin Ajala Eti Nyin Melo?

Ọgbẹni kan, ọjọgbọn oniṣegun ti a npe ni Dokita James H. Steele lo sọ wipe, iṣọra di ọwọ ẹnyin Ajala Alajanibọn nitoripe bi o ti wu ki aja kere to arun digbolugi mbẹ lara rẹ. Nitorina, ẹ maṣe jẹki nwọn la ọwọ nyin bẹni ki ẹ maṣe jẹki nwọn fi ahọn l'a oju apa tabi oju egbo ti o ndun nyin.

Digbolugi jẹ arun buruku ti o nja at'enia ati eranko logun. Nilẹ awọn Hausa nilu kan ti a npe ni Daura, ọmọbinrin kan, ti a npe ni Amina ni egbo lẹsẹ rẹ, ṣugbọn nigba gbogbo ni aja wọn ma nfi ahọn le oju egbo na.

Ko ju iwọn ọdun mẹta lọ nigbati arun digbolugi dagba si ara Amina nṣe ni arun ṣubu-ṣere ati aiperi bẹrẹ si yọ lẹnu. Bi ko ba si opelopẹ Dokita J. H. Steele, nigbati o di abẹrẹ mẹjọ ti o fun ọmọ na, lo to ri alafia.

Ko si aja ti ko ni arun digbolugi lara. Bi aja digbolugi ba bu enia jẹ, arun bi warapa, ṣubu-ṣere, tabi aiperi ti o le doju ti enia larin ilu yio ma yọ oluwa rẹ lẹnu-

Igbọran san ju ẹbọ lọ.


## Polowo Ọja Re Sinu Iwe Irohin Eleti - Ọfe

## Abo Iwadi Igbimo Ibile Ibadan

(O bẹrẹ l'oju ewe kinni)



MR. ADEGOKE ADELABU

Oluwadi na ko ṣai ba iwe irohin Nigeria Tribune wi fun inira ti o gbe ti ijọba na ni akọbere a si sọ pe iru Ọlọla A. M. A. Akinloye gẹgẹbi olori Ijọba ki ba ti lọwọ ninu ọtẹ kọkan si Ijọba Ibilẹ Ibadan. O si kansara si iwa pẹlu suru ati ọgbọn ti Ọlọla F. Rotimi Williams gẹgẹ bi Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ti o di ọrọ yi mu, wipe bi oti'ẹjẹpe oṣu sẹhin ni wọn ti nfa lọtun losi pẹlu Irohin abẹlẹ, o kọ ki wọn ṣe iwadi kọkan rara- Nigbati o wa de oju ibiti o di tulasi, ni o ṣeṣẹ iọgonu.

Bi o ṣe wipe o ti ni ijọba Ibilẹ ninu ni gẹgẹbi ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ, bi awọn kan ti nro, iba ti fi aṣẹ si iwadi lọjọ to ti pẹ s'ẹhin. Oluwadi damọran wipe ki aye fi awọn ope sinu igbimọ mọ nitoripe wọn kole ka, nwọn ko si le kọ, nwọn kole mọ bi nkan ti nlọ si rara, wọn kan wa bi aworan ni ninu Igbimọ, o si tun sọ wipe ki Ijọba l'agbara lati le ma da ẹnikẹni duro ninu Igbimọ ti a ba ti leri pe o jẹbi owo ijẹkujẹ tabi ibajẹ, fun bi ọdun mẹta, ki olotu ijọba ti gbogbo-gbo tabi ti ẹkun ye yọnu si awọn oṣiṣẹ Ijọba Ibilẹ pẹlu.

Ki alaga Ijọba Ibilẹ maṣe ṣe alaga fun Igbimọ kekere kọkan, ati pe ki ẹnikẹni maṣe ṣe alaga fun Igbimọ kekere ju meji lọ. ki awọn Alatako ma a wa ninu gbogbo Igbimọ, ki agbara tubọ pọ fun awọn Local Goverment inspectors, ki a si tun ofin ati aṣa ilẹ wa ṣe fun asiko yi.

## Tokotaya Wuye N'lu Ijebu

(O bẹrẹ l'oju ewe kinni)

sibẹ igbadun ariya na ga pin. Ka ma tun sọ ti awọn to dari lati Owu wa si Agọ Iwoye ninu awọn to tun yayi ariya yi ni Alufa Alayande, Ọgbẹni T. L. Oyesina ati Iya-fin rẹ, Ọgbẹni T. O. Ogunkọya, S. A. Balogun L. S. Ogunlesi, Ọlọla S. O. Awokọya C.B.E. Ọlọla V. Duro Phillips, Oloye M. A. Okupẹ, (Agbọnmagbẹ) Oloye E. O. sotuminu, Ọgbẹni J. P. Ala ati awọn oloye ati gbogbo ọrẹ to gbọ to wa la ki ku ọdun, ire a kari, a dele ba ire o, Amin.

## Awon Asiwere Meji Fa Ijongbon L'oke Ebute Metta

Agan bẹ l'owurọ ọjọ Alamisi ni ọja Oyingbo (Ebute - Mẹtta) nigbati awọn obinrin meje ti awọn mejeji jẹ aṣiwere enia ti nwọn fi apakan gbangba teju ti a npe ni ọja Ikẹja ni Ebute - mẹtta ṣe ile ibugbe wọn wọn bẹrẹ si fa kokowa lori wipe nwọn nṣe idiwọ fun arawọn nibi ibugbe wọn.

Bi ọrọ na ti lọ niyi:-

Ọkan ninu awọn were obinrin wọnyi dide rin lọ si arin ọja Oyingbo, ki o to de, ekeji ti sun diẹ mọ aye ibiti eyiti o rin lọ na fi ṣe ile tirẹ nigbati ẹlẹgiri de, o bi lere wipe ki ni ohun ti o mu ọ d'ẹhin? idahun ti were keji ni wipe abi wọn s'epe fun ọ?

K'amafa ọrọ gun, awọn mejeji fija p'ẹta, ko si enia to le sun mọ wọn lati la wọn ni ija, afi igbati awọn oṣiṣẹ ilu de (Town Council) ni wọn la ija na.

Enjoy Your Own

— Songs —



Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC :- yours, on obtainable from is

The Association Of Nigeria Gramophone Dealers . . . .
THROUGHOUT . . . . . . .
. . . . . NIGERIA . . .




## Mbonu Ojike Jebi Owo Ibole

Oluwadi owo-ijẹkujẹ, ti a npe ni owo ibọlẹ, ti Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun (Eastern Government) yan lati ṣe agbeyẹwo ọrọ wuru - wuru larin awọn ọlọla ti nwọn yan to di okun Ijọba na mu ni Oluwadi ṣe ipinnu afisun ti ejọ ti Ọlọla Mbonu Ojike- Olotu eto inawo ti Ijọba Ila-Orun jẹbi wipe, o gba owo ibọlẹ lori iṣẹ kan.

Oluwadi si wipe awọn yio ṣe eto abọ iwadi na fi ranṣẹ si Gomina Ila - Orun.



MBONU OJIKE

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Nonyelu ti iṣe Loya Ọgbẹni Ojike fa ọrọ diẹ pẹlu Oluwadi. Ọgbẹni Ikpeazu, wipe on fẹ sọrọ ti Oluwadi sọ wipe, awọn koi fẹ lati gbọ ọrọ rẹ.

Nigbati Ọgbẹni Koofrey dasi wipe ki a gba laiye ki o sọ t'ẹnu rẹ, ni Ọgbẹni Nonyelu ba ka apakan ninu ofin to sọ wipe Oluwadi ko lagbara lati ka abọ iwadi si ta fun awọn enia gbọ laiko iti fi ranṣẹ si Gomina,

Oluwadi si sọ fun wipe awọn gbọ ohun to sọ o.

Ohun ti Oluwadi keji tun sọ ni wipe gbogbo nkan to ba ti idi rẹ jade awọn gbe bi enia ba tilẹ titori ire ilu rẹ ku, ogo ni yio jẹ

### SALIMỌNU FỌLAMI D'OLOGBE

EKO—Agbọju igbanu ni iku Ọgbẹni Salimọnu Folami eyiti a gbọ ni owurọ oni Friday January, 1956.

Ọgbẹni Fọlami ni a gbọ wipe o ṣe agbako jamba Moto ni orumọju Alamisi Thursday January 18, 1956 nigbati o ndaribọ lati oko rẹ ni Ojokoro.

A gbe lọ si ile iwosan (General Hospital) ni orumọju na, ṣugbọn bi gbogbo awọn Oniṣegun ti sa agbara wọn to, Ọlọjọ kọ

Fun opọlọpọ ọdun ni Ologbe yi fi ṣe iṣẹ ni Ile Ifi Owo pamọsi British West African Bank ati National Bank ni Eko. Oluwa ki o fi Ọrun kẹ Ologbe yi. Ologbe yi to ẹni ọdun Mẹtadinlọgọta.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone